# ORIN IBILE IJEBU IMUSIN

1 Ijebu-Imusln
Ilu ola Igbanl
Ile ominira
Odo Alade Oba
Budo akoni l'oju ogun
Orin-din-nirinwo ilu Ie meta
Orin-din-nirinwo ilu Ie meta
N'ibi nwon ns'iku ejo
Laiye igbani,
Ojowo ile Ijebu
Edumare ye jowo ran mi lowo
Ki nle ma wa ire re o
Titi lae
} 2ce

2 Ijebu-Imusin
Ilu to teju
N'ibi orisun omi fadaka,
L'eti Ebute Iyemoji o,
Erelu oja ile Ijebu,
Ajina, anokoru,
Orita Oko ona mejila,
Tin je ife-Owodaiye,
Edumare ye jowo ran mi lowo
Ki nle ma wa ire re o
Titi lae
} 2ce

3 Oluwa Edumare
Oba Olu Imusin
Jowo gbe ilu mi leke,
Je ki o bori ota o,
Te awon enia inu re lorun
Ki won ri t'aje se
Bukun won n'ile-Oluwa
Bukun won n'ile
Bukun fun won I'ajo
Bukun won kari kari
Oluwa wo wa o
Ni ile Imusin
Edumare ye jowo ran mi l'owo
Ki nle ma wa ire re o
Titi lae
} 2ce

4 Kabiyesi Oba Alaiye
A juba re Oba Oloko
Oba Olu Imusin
Kabiyesi Oba Magunsen,
Oba Itamarun, Imusin
Kabiyesi Oba Obelu
Oba Esure Imusin,
Kabiyesi Oba Ogirimadagbo
Oba Ilodo, Imusin
Kabiyesi Oba Oyebola
Oba Igbaga Imusin
Kabiyesi Oba Elesugbon
Oba Esugbon, Imusin
K'ade pe l'ori o
Ki bata pe l'ese
} 2ce
Ke joba pe titi
Ki' joba yin tu wa lara
Ka rire laiye, Oluwa
Ke rire laiye
K'aiye yin niyo
Ke joba pe titi
Kigba yin toro,
B'omi afowuro pon,
Eyin Alaiyeluwa Oba
Edumare ye jowo ran mi l'owo
Ki nle ma wa irere o
Titi lae
A-a-se. A-min o. A-a-se.
} 2ce